# Ìdámọ̀ràn Fìdíhẹ ẹ fún Ète Ajẹmáṣà Ìlú Medway.

Àjọ Olùdámọ̀ràn GJG, Oṣù Agà, Okòó-lé-lẹ́gbàá Ọdún.

Àjọ Olùdámọ̀ràn GJG ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Alájùmọ̀ṣepọ̀ Ajẹmáṣà ti Ìlú Medway àti àwọn Ìgbìmọ̀ Ìlú Medway láti jọ ṣàgbéga Ète Ajẹmáṣà tuntun fún Ìlú Medway.  Ìwé yìí jẹ́ìsọníṣókí Àfojúsùn, Àmúyangàn àti àwọn Kókó Ọ̀rọ̀ Pàtàkì tí yóò ṣègbèlẹ́yìn Ète náà– èyí ni àbáyọrí ìdámọ̀ràn náà títí di òní.

## Kí ni ìdí ète ajẹmáṣà?

**Ète ajẹmáṣà gbọ́dọ̀ ṣe ìpinnu – láti lè sọnípa àfojúsùn tó gbòòrò àti láti sàfihàn ìrètító ga jù lọ fún ìlúkílùú àti àwọn ènìyàn rẹ̀.**

Ète tuntun fún Okòó-lé-lẹ́gbàá Ọdún síỌgbọ̀n-lé-lẹ́gbàá Ọdun gbọ́dọ̀ ṣàfihàn bíàṣà ṣe jẹ́ pàtàkì sí fún ọjọ́-ọ̀la Ìlú Medway, kí ó sì tún fún gbogbo ènìyàn ní àǹfààní láti kópa tàbí dá sí ìgbé ayé ajẹmáṣà ìlú náà.

Ọ̀nà tí a fẹ́ tọ̀ ni láti ṣe ìrànwọ́ ká jọ ṣẹ̀dáàjọgbékalẹ̀ àfojúsùn tó kálé-káko fún àṣà níìlú kan. Èyí á lè so pọ̀ mọ́ ẹ̀ka ajẹmáṣà fún àwọn ọ̀rọ̀ tó fẹjú (bí àpẹẹrẹ, ìwànírọ̀rùn), èyí tó foríṣọ àfojúsí àwọn lẹ́gbẹ́lẹ́gbẹ́ àti ilé-iṣẹ́ alámòójútó.

Fún àkókò ráńpẹ́, Ète Ajẹmáṣà wa yìí yóòṣe àtúnṣe sí àwọn èròńgbà àti ìṣesíọmọnìyàn, á sì tún darí wa láti lè jẹ èrè tó jẹ́tàwùjọ àti tọrọ̀-ajé.  Bí a bá wá wo àkókòọlọ́jọ́-gbọọrọ, ó gbọ́dọ̀ bojúwò láti yí Ìlú Medway padà.

## Ọ̀gangan ibi tí ìdámọ̀ràn náà dé dúró

**Gẹ́gẹ́ bí ara ìdámọ̀ràn ọ̀hún, Àjọ Olùdámọ̀ràn GJG ti bá onírúurú àwọn ènìyàn Ìlú Medway sọ̀rọ̀.**

Àwọn ènìyàn bí:

- Àwọn olùgbé tí wọ́n ń ṣojú fún oríṣirísi agbègbè – ó bẹ̀rẹ̀ látorí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ Ilé-Ẹ̀kọ́ Girama Rochester títí dórí àwọn Òṣìṣẹ́fẹ̀hìntì nínú Ẹgbẹ́ Àwọn Aláwọ̀dúdúti Ìlú Medway, àwọn t'ọ́n mọ̀sí Dírágónì t'ọ́n jọ ń ṣiṣẹ́ pọ̀ fún ẹgbẹ́ alájùmọ̀jẹpọ̀, àtiàwọn ẹgbẹ́ ahunṣọ t'ọ́n wà ní Gbọ̀ngànÌkówèépamọ́síkà ní Walderslade.
- Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ tó Àádọ́rin àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn gbọ̀ngbọ̀n láti oríṣiríṣi ẹ̀ka bí i ti ètòajẹmáṣà, ètò ìjọba ìbílẹ̀, ètò ìlera, ètò iṣẹ́àtinúwá àti agbègbè, ètò ẹ̀kọ́, ètò ọrọ̀-ajéàjòjì, ètò ìsọdọ̀tun àti ètò ìdàgbàsókè ọrọ̀-ajé.
- Níbi Ìjókòó Ìta gbangba nínú Oṣu Bẹẹrẹ, Okòó-lé-lẹ́gbàá Ọdún, ó lé ní Àádọ́jọ àwọn ènìyàn bí i oníṣẹ́-ọnà, olùdásílẹ̀, olùkọ́ni, òṣìṣẹ́ ìgbìmọ̀ àti òṣìṣẹ́afúnnimágbàẹlẹ́yinjú-àánú.

# Àfojúsùn.

Àfojúsùn fún Ìlú Medway nílò láti di gbígbéga àmọ́, ó gbọ́dọ̀ ṣe àfikun àwọn ìlànà wọ̀nyí:

**Àṣà jẹ́ ọ̀gangan ohun tí a lè fi sọ àsọyénípa ìdánimọ̀ Ìlú Medway. Àṣà wa ló sì jẹ́ kíÌlú Medway jẹ́ ibi tó dára jù láti gbé, láti ṣiṣẹ́, láti kẹ́kọ̀ọ́ àti láti ṣàbẹ̀wò sí i.**

**Ipa rere wọ̀nyí takùn tayọ ọjọ́ iwájú àwọn ẹ̀ka bí i ètò ìlera àti ìwàníròrùn, ètò ẹ̀kọ́, ètò ìsọdọ̀tun, ètò ìṣedéédé àwùjọ àti ìwúrí àwọn ará ìlú.**

**Ẹka ajẹmáṣà wa jẹ́ èyí tó kún fọ́fọ́, tóyàtọ̀, tó sì tún wúni lórí láti lé ṣe àfihàn àwọn ènìyàn wa àti ìlú wọn lóríṣiríṣi.  A níláti gbé ẹ̀ka yìí ga kí a bàá lè pín ohun tí a nífún gbogbo ayé lọ́nà tó dára jù lọ.**

**Ṣíṣiṣẹ́pọ̀ yóò jẹ́ kí ìfàyègba ajẹmáṣàwa lókun sí i. A lè rí èyí ṣe nípa ṣíṣèdáonírúurú àjùmọ̀ṣepọ̀ tó lè pẹ́ kánrin-kése, láàárín Ìlú Medway àti àwọn ìlú tó jìnnàréré.**

**Ẹnì kọ̀ọ̀kan  ní ẹ̀tọ́ láti kópa nínú ètòajẹmáṣà àti àwọn èrè tó wà nínú rẹ̀. A ó sìrí i dájú pé, àwọn àǹfààní wọ̀nyí ṣí sílẹ̀fún gbogbo ènìyàn.**




Medway Cultural Strategy 2020-2030: Values and Themes
http://medwayculturalstrategy.co.uk/
GJG Consultancy, May 2020

# Àmúyangàn.

Àwọn Àmúyangàn wọ̀nyí máa ń ṣe àtúnṣe sí gbogbo abala bí a ṣe ń ṣèdá àti àgbékalẹ̀ Ète Ajẹmáṣà – èyí ni àwọn ìlànà tí a ṣe àbápín rẹ̀ láti lè tọ́ wa sọ́nà fún ọdún mẹ́wàá ó lé síi:

**À ń jùmọ̀ ṣiṣẹ́ pọ̀** Èyí ní í ṣe pẹ̀lú jíjẹ́ẹni tó nínúure, tó finú hàn, tó sì tún ní àtinúdá.  Àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ dáadáa máa ń níàgbọ́yé lórí àwọn ohun tí ẹlòmìíràn nílò, wọn a máa bọ̀wọ̀ fún ààlà, wọn a sì máa wá ohun rere.

**À ń gbé ipa tí ìṣe wa lè ní lórí ìwọ̀n kí a tótẹ̀ síwájú** A ṣe ìgbàláàyè fún ṣíṣe ẹ̀dàákọ̀kọ́, dídán an wò, ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àti àmújọ̀lọ̀ rẹ̀ láti rí i dájú pé Ète náà jẹ́ ìdáhùn sí àyípadà.

**Apètepèrò ni wá, a sì tún máa ń ro àròjinlẹ̀tò dá lórí àkókò ọlọ́jọ́ gbọọrọ** Nínúohunkóhun tí a bá ń ṣe, à ń mú àwọn àfàyọọlọ́jọ́ gbọọrọ lọ́kùn-ún-kúndùn, kí á lè rí i dájú pé wọ́n tọ́ wa sọ́nà pẹ̀lú ohun Àmúyangànkí a sì mú Àfojúsùn wa wá sí ìmúṣẹ.

**Iṣe wa jẹ́ èyí tó lè pẹ́ kánrin-kése, kó sì tọ́jọ́ní àyíka** A dá iṣẹ́ ẹ̀ka ajẹmáṣà mọ̀ pé ó ńléwájú nínú àyípadà àti ìgbéláruge ojúṣe ajẹmáyìíká láàárín àwọn agbègbè wa.

**À ń fún tolórí-tẹlẹ́mù ní àyè tó pọ̀ sí i** A gbọ́dọ̀ tànmọ́lẹ̀ sí gbogbo àwọn ará ÌlúMedway, ká bọ̀wọ̀ fún ìyàtọ̀ wọn, ká sì ṣe ìdánimọ̀ bí onírúurú ẹ̀yà ṣe jẹ́ àǹfààní tó ga jù lọ – èyí ni orísun àbá àti àrà ọ̀tun.

**A dá àṣà mọ̀ bí ohun tó ṣe pàtàkì síìwàníròrùn** A mọ rírì ipa rere tí àṣà àti iṣẹ́-ọnà ń kó lórí ìlera àwọn ènìyàn nípa ti ara, ti ẹ̀mí àti ti iyèọpọlọ.

# Àwọn kókó ọ̀rọ̀

Àwọn kókó ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni ìpilẹ̀sẹ̀ tó jẹ́kànńpá, èyí tí a gbé Ète kà tó fi ró gẹ́gẹ́. Wọ́n ń pèsè ìhun, àtìlẹyìn àti ààlà:

**Àsopọ̀mọ́ra** Bí a ṣe ń so pọ̀, tí a sì ń bára ẹni sọ̀rọ̀ ṣe pàtàkì. Àsopọ̀mọ́ra ń jẹ́ ká ní ọ̀pọ̀oríṣiríṣi ọ̀nà – ìgbaniníyànjú tó jẹ́ ìlànà 'bù-fún-mi-n-bù-fún-ọ' àti ìfọkàntán láàárín àwọn agbègbè.

**Ọ̀kánjúwà tí a ṣe àbápín rẹ̀** Ríronú nípa bíìṣe wa ṣe jẹ́ àǹfààní fún tolórí-tẹlẹ́mù, àti bíàfojúsí wa ṣe wà lórí àgbékalẹ̀ Àfojúsùn wa àti àgbáríjọ àǹfààní tó kan mùtúmùwà.

**Awon Àyè àti Ìlú** Kíkọ́ àwọn àyè láàárín Ìlú Medway láti fàyè gba iṣẹ́ àtinúdá, kó sì jẹ́ibi tí àwọn ènìyàn le wọ̀ nírọ̀rùn; ká tún fi àǹfààní àpẹẹrẹ yìí hàn fún agbègbè àti fún títọ́jọ́.

**Láti Ìgbèríko lọ dé àwọn Ìlú Ńláńlá** Èyí ni ọ̀nà gbogbogbòò tó kógo já 'láti ìgbèríko lọ dé àwọn ìlú ńláńlá'; kí á lè ṣe àmúdàgbà àtinúdáẹ̀kọ́ nípa 'bójú-ojọ́-ṣe-rí', èyí tó ní ìlera tópéye, níbi tí gbogbo ìpilẹ̀sẹ̀ á ti ní àtìlẹyìn tógbọgbọ́n– àwọn ọ̀nà tí à ń tọ̀ tẹ́lẹ̀ láti òkèdé ilẹ̀ kò tó láti lè sèso rere.

**Àdéhùn Agbègbè** Ṣíṣí ilẹ̀kùn ọ̀nà ìfarajìn wa sílẹ̀ gbayau kó bàá fàyè gba 'àṣà fún tolórí-tẹlẹ́mù' nípa kíkàn sí ọ̀pọ̀ ènìyàn, kí á sì fún wọn láyè láti kópa nínú àṣà ní ọ̀nàkọnà t'ọ́n bá fẹ́.

# Ẹ bá wa sọ̀rọ̀.

A fẹ́ kí ẹnì kọ̀ọ̀kan yín jọ̀wọ́, sọ èrò yín fún wa pẹ̀lú pípari Ìwádìí wa lórí Ayélujára (https://www.smartsurvey.co.uk/s/Medway2020/).

A rọ̀èyin Ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́, kí ẹ ka ẹ̀dà kíkún Ìjábọ̀wa (https://tinyurl.com/y95bwnt3).

Bí ẹ bá fẹ́ wádìí síwájú sí i, ẹ jọ̀wọ́, ẹkàn sí ìkànnì medwayculturalstrategy.co.uk lóríayélujára.